**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**TÍTẸ̀ ÀWỌN EJÒ ÀTI ÀKÉÈKÉ MỌ́LẸ̀ (2)**
**OṢÙ KỌKÀNLÁ, ỌDÚN 2026**
Ìwé Mímọ́ Kíkà: Orín Dáfídì 118
Ìjẹ́wọ́: Lúkù 10:19

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji bàlé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíjibo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá, jẹ́ kí Ẹ̀mí Mímọ́ kún mi l'ọ́tun, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá, jẹ́ kí gbogbo agbègbè ayé mi tíkò tí wópalẹ̀ gba ìwópalẹ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Bàbá, kún mi pẹ̀lú iná Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.
8. Olùwa, jẹ́ kí gbogbo ìdè tó lòdì sí agbára nínú ayé mí fọ́, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo agbára àjẹ́, tó nmu ẹ̀jẹ̀ ìgbé-ayé ẹ̀mí mi, kú, ní orúkọ Jésù.
10. Ògo Ọlọ́run, ṣíjibò mí, ní orúkọ Jésù.
11. Okun Ọlọ́run, rómilágbára, ní orúkọ Jésù.
12. Agbára ìpìlẹ̀ ìyówù, tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìdàgbásókè ẹ̀mí mi, gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo àjàgà tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìdàgbásókè t'ẹ̀mí nínú ayé mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo ìwà apanirun, tí wọ́n gbékalẹ̀ láti fi ayé mi ṣòfò, kú, ní orúkọ Jésù.

15. Gbogbo agbègbè tíkò tí nì ìtúsílẹ̀ pípé nínú ayé mi, gba ìtúsílẹ̀ pípé nípa iná, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo owúṣúwuṣù t'ẹ̀mí, kákúrò lójú ìríran mi, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo ẹ̀mí oògbé, mo gbè ọ sin lónìí, ní orúkọ Jésù.
18. Idì ìgbé-ayé ẹ̀mí mi yóò gòkè nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
19. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, pa gbogbo iṣẹ́ òkùnkùn nínú ayé mi run, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo ilẹ̀kùn tí ó ṣí sílẹ̀ fún ọ̀tá agbára t'ẹ̀mí nínú ayé mi, tìpa, ní orúkọ Jésù.
21. Olúwa, jẹ́ kí omi ìyè ṣàn sí gbogbo agbègbè tó ti d'òkú nínú ìgbé-ayé ẹ̀mí mi, ní orúkọ Jésù.
22. Ejò àti àkéèké ìpìlẹ̀ ìyówù, tí wọ́n ṣètò sínú ayé mi láti pa ìgbàlà mi run lọ́jọ́ iwájú, kú, ní orúkọ Jésù.
23. Ọlọ́run Èlíjàh, dìde, fún mi ní agbádá agbára, ní orúkọ Jésù.
24. Ohunkóhun tí wọ́n gbìn sínú ayé mi, tó n dúró láti farahàn lọ́jọ́ iwájú, láti jẹ́ kí n pẹyìndà, gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.
25. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo àlejò sá kúrò nínú ẹ̀mí mi, jẹ́ kí Ẹ̀mí Mímọ́ gba iṣàkóso, ní orúkọ Jésù.
26. Olúwa, gbé ìgbé-ayé ẹ̀mí mi lọ s'órí-òkè ténté, ní orúkọ Jésù.
27. Bàbá, jẹ́ kí ọ̀run ṣí í, kí ògo Ọlọ́run bàlé mi, ní orúkọ Jésù.
28. Bàbá, jẹ́ kí àmì àti àrà jẹ́ ìpín mi, ní orúkọ Jésù.
29. Olúwa, ṣí ojú àti etí mi láti gba àwọn ohun ìyanu látọ̀dọ̀ Rẹ, ní orúkọ Jésù.
30. Olúwa, fún mi ní ìṣẹ́gun lórí ìdanwò àti àwọn ète sàtánì, tí wọ́n yàn láti jẹ́ kí n pẹyìndà, ní orúkọ Jésù.
31. Olúwa, dá iná sínú ìgbé-ayé ẹ̀mí mi, kí n balè d'ẹ́kun dídẹdò nínú àwọn omi tíkò lérè, ní orúkọ Jésù.
32. Olúwa, tú ahọ́n iná Rẹ sílẹ̀ sórí ayé mi, kí O sì jó gbogbo èérí t'ẹ̀mí tó mbẹ nínú mi, ní orúkọ Jésù.
33. Bàbá, jẹ́ kí n peebi àti poùngbẹ fún òdodo, ní orúkọ Jésù.
34. Olúwa, jẹ́ kí n gbilẹ̀, kí n fẹsẹ̀múlẹ̀ nínú igbàgbọ́ mi, ní orúkọ Jésù.

35. Olúwa, wó gbogbo agbègbè ìpadàsẹ́yìn nínú ìgbé-ayé ẹ̀mí mi sán, ní orúkọ Jésù.
36. Olúwa, ṣí òye mi nípa Ìwé Mímọ́, ní orúkọ Jésù.
37. Olúwa, jí mi dìde kúrò nínú oorun t'ẹ̀mí ìyówù, kí O sì ràn mí lọ́wọ́ láti gbé ìhámọ́ra ìmọ́lẹ̀ wọ, ní orúkọ Jésù.
38. Olúwa, fún mi ní ìṣẹ́gun lórí gbogbo iṣẹ́ ẹran-ara, kí O sì ràn mí lọ́wọ́ láti wà ní gbàgede ìfẹ́ Rẹ, ní orúkọ Jésù.
39. Olúwa, fún mi ní ìpeebi nlá fún ògidì wàrà àti oúnjẹ líle nínú ọ̀rọ̀, ní orúkọ Jésù.
40. Olúwa, rómilágbára láti yẹra fún ohunkóhun tàbí ẹnikẹ́ni tí ó lè gbà ipò Ọlọ́run nínú ọkàn mi, ní orúkọ Jésù.